**STRONG TOWER ACADEMY: YORÙBÁ NOTE.**

**OLÙKỌ́: AYA ÀJÀYÍ**

**KÍLÁSÌ: J.S.S.1**

**Ọ̀SẸ̀: KẸRIN.**

**KÓKÓ-IṢẸ́: IṢẸ́ Ọ̀RỌ̀-ÌṢE nínú gbólóhùn èdè Yorùbá. ( The work of verb in the sentences)**

Ọ̀rọ̀-ìṣe ni ẹ̀mi gbólóhùn. Òun ni òpómúléró to n tọ́ka iṣẹ̀lẹ inú gbólóhùn. O máa n sọ ohun tí olùwà ṣe B.A

Kọ́lá **jẹun**

Mo **lọ** sí ilé-ìwé.

Bọ́lá n **ro** àmàlà ni orí iná.

IṢẸ́ Ọ̀rỌ̀-IṢE:

1. Ọ̀rọ̀ – iṣe: Ni o máa n tọ́ka ìṣẹ̀lẹ̀ nínú gbólóhùn. B A.

   Múrí **lọ** sí Ilé-Ifẹ̀.

   Ṣọlá **ra** ìwé .

   Àwa **wọ** aṣọ

2. Ọ̀rọ̀-iṣe lè ṣiṣẹ́ bíi odindi gbólóhùn, kí o sì gbé òye ohun tí a fẹ́ jáde. B A.

   Dìde, sùn, jáde, sáré, jẹun.

3. Ọrọ - iṣe lè ṣiṣẹ́ ìyísódì láti fi pàṣẹ. B.A

   Má **dìde**

   Má **sùn**

   Má **sáré**

4. Ọ̀rọ - ìṣe lè ṣiṣẹ́ ìbéèrè nípa lílo ọ̀rọ̀ aṣèbéèrè. B .A

   Bísí **dà**?

   Olú ń **kọ́** ?

**ÌGBÀ: Kejì (Second period)**

**KÍLÁSÌ: J.S.S. 1**

**ORÍ-Ọ̀RỌ̀: <u>Àwọn ìyàtọ̀ tó wà láàrín lẹ́tà Gbẹ̀fẹ́ àti Aigbẹ̀fẹ́</u>**

| **Lẹ́tà Gbẹ̀fẹ̀** | **Lẹ́ta Aigbẹ̀fẹ́** |
|---|---|
| 1. Àdirẹ́si kan | Àdirẹsì méjì |
| 2. Kò ni akọlé | Ó ní àkọlé |
| 3. A lè ṣe ẹ̀fẹ̀ nínú lẹ́tà Gbẹ̀fẹ̀ | A kò le ṣe ẹ̀fẹ̀ nínú lẹ́ta Aìgbẹ̀fẹ̀ |
| 4. Orúkọ̀ àbísọ níkan ni a gbọ́dọ̀ kọ | Orúkọ bàbá ẹni àti orúkọ àbísọ |
| 5. Kò ni àmì ìfọwọ́sí | Ó máa ń ní àmì ìfọ̀wọ̀si. |

**3rd Period**

**KÍLÁSI:** J.S.S. 1.

ORÍ-Ọ̀RỌ̀: **IṢẸ́ ÌLÙ LÍLÙ, AWỌN TÓ N LU WỌ́N.**

Ìlú lílù jẹ́ iṣẹ́ iṣẹ̀nbáyé ilẹ̀ Yorùbá. Ìran àwọn Àyan tàbi àwọn ọmọ tí wọn tọrọ lọ́wọ́ Àyángàlú. Àwọn ìran onilù ni wọn n jẹ́ orúkọ bíi: Àyangàlú, Àyandélé, Aláyandé, Àyanbùnmu, Àyanfàlú, Àyanwọlé. Abbl.

**OrìṣÌÌ ìlù tó wà àti ìlò wọn.**

Iṣẹ́ amúludùn ni iṣẹ́ Àyan. Wọn n lùlù ni oríṣìíríṣìí Àṣeyẹ/Ayẹyẹ. Oríṣìíríṣìí ìlù ni ó wà. Díẹ̀ nínú wọn ni:

Dùndùn, Gángan, Àdàmọ̀, Ìbẹ̀nbẹ́, Igbin, Àgẹ̀rẹ̀, Oṣùgbó, Bàtá, Kòso, Kíríboto, Gbẹ̀du, Ṣákárà, Sáǹbà, Apẹpẹ, Ìpèsè, Agogo, Àgídìgbo, abbl.

Àwọn ohun tí wọn fi ń ṣe ìlù ni: Igi, Awọ, Ọsán.

**IṢẸ́-ÀṢETILÉWÁ. (Assignment)**

**Ọ̀sè Kẹrin.**

**Kilaasi: J.s.s. 1**

1. Kínni ọ̀rọ̀-iṣe?

2. Oríṣìí Àdirẹsi mélòó ni o wà ní lẹ́tà Àigbẹ̀fẹ̀?

3. Lẹ́tà wo lóní àmi ifọwọsí**?**

4. Àwọn Ìdílé Onílù ni à ń pè ni ___________

5. Dárúkọ oríṣìí ìlù Márun-un?